# Lẹ́yìn tí o Bèrè fún Ilé Àìwọ́n: Àwọn Àkójọ Àyẹ̀wò àti Ohun Àmúlò

*Ìsopọ̀ Ilé NYC*

*[PAGE 1]*

## NÍPA ÌTỌ́NI YÌÍ

Àwọn ìwé ìbèrè fún ilé àìwọ́n ni a ń yàn fún àtúnyẹ̀wò nípasẹ̀ ìlànà tẹ́tẹ́ oríire.

Tí nọ́mbà rẹ bá jẹyọ nínú tẹ́tẹ́ oríire náà, tí ìbèrè rẹ sì farahàn bí èyí tó kún ojú òṣùwọn, a ó fìwé pè ọ́ láti ṣètò ìpàdé láti ṣàrídájú àmúyẹ rẹ. Ìpàdé náà wà láti ṣàtúnyẹ̀wò àwọn ìwé tó bá àlàyé inú ìwé ìbèrè rẹ wá.

Àwọn ètò ìpàdé ni a máa ń sábà ṣe láti oṣù méjì sí mẹ́wàá lẹ́yìn ọjọ́ tí ìbèrè náà ti dópin. A ó ni kí o mú àwọn ìwé nípa àwọn tí yóò máa gbé pẹ̀lú rẹ wá, iye owó àpawọlé ẹnìkọ̀ọ̀kan tí yóò máa gbé pẹ̀lú rẹ, ibùgbé tí o wà lọ́wọ́lọ́wọ́, àti àlàyé míràn.

Ìtọ́ni yìí ń ràn ọ́ lọ́wọ́ láti gbáradì fún ìpàdé náà. Ó ń ṣàkójọ àwọn ìwé tí o le ní láti mú dání, ó sì ń fún ọ ní ìmọ̀ràn lórí bí o ti ṣe lè rí ẹ̀dà àwọn ìwé tí o nílò, àti bí o ti ṣe lè pèsè wọn sílẹ̀.

*[PAGE 2]*

## ÀWỌN ÌWÉ ÀKỌSÍLẸ̀ MỌ̀LẸ́BÍ

Tí a bá kàn sí ọ fún

ìpàdé kan láti ṣàrídáju àmúyẹ rẹ, a ó sọ fún ọ pé kí o mú ÀWỌN Ẹ̀DÀ ìwé àkọsílẹ̀ rẹ tó jẹ́rìísí àwọn ènìyàn inú mọ̀lẹ́bí rẹ wá. Jọ̀wọ́ máṣe mú ojúlówó àwọn ìwé náà wá, àyàfi tí a bá bèrè. Àwọn ẹ̀dà àwọn ìwé wọ̀nyí yóò wà nínú fáìlì – o kò ní gbà wọ́n padà.

Olùkọ̀lé náà yóò jẹ́ kí o mọ irú àwọn àkọsílẹ̀ tí o ní láti mú wá. Gbogbo àwọn ìwé ìsàlẹ̀ yìí ni a le bèrè.

## ǸJẸ́ O NÍ ÀWỌN ÌWÉ WỌ̀NYÍ BÍ?

### Ibùgbé Tí o Wà Lọ́wọ́lọ́wọ́

- ☐ Ẹ̀dà ìwé àdéhùn ilé yíyá rẹ ìsinsìnyí, bí o bá yá ibùgbé rẹ gbé. Tí o kò bá ní ìwé àdéhùn ilé yíyá, lẹ́tà àrídájú tí a fọwọ́sí lábẹ́ òfin láti ọ̀dọ̀ onílé rẹ.
- ☐ Ẹ̀dà ìwé ẹ̀rí owó-sísan fún ìyálégbé tí oṣù mẹ́ta (3) sí oṣù méjìlá (12) tàbí àwọn ìwé pàṣípààrọ owó ìyálégbé tí a fagilé.
- ☐ Ẹ̀dà ìwé owó iná tàbí ti gáàsì rẹ titun jùlọ (ní orúkọ rẹ, tó sì ń ṣàfihàn àdírẹ́ẹ̀si rẹ ìsinsìnyí).
- ☐ Ẹ̀dà ìwé owó ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ rẹ rẹ titun jùlọ (ní orúkọ rẹ, tó sì ń ṣàfihàn àdírẹ́ẹ̀si rẹ ìsinsìnyí).
- ☐ Tí o kò bá yá ibùgbé rẹ gbé, tí o sì ń gbé pẹ̀lú ẹlòmíràn, mú lẹ́tà àrídájú tí a fọwọ́sí lábẹ́ òfin wá, láti ọ̀dọ̀ ẹnití ẹ jọ ń gbé, pẹ̀lú ẹ̀dà ìwé àdéhùn ilé yíyá rẹ̀ àti ẹ̀dà ìwé owó àwọn ohun àmúlò rẹ.

***Níbo ni mo ti le ṣe àrídájú àwọn ìwé lábẹ́ òfin?***

- Àwọn aṣojú ìṣàkóso ohun ìní àti àwọn ilé-iṣẹ́ owó-ìlú abẹ́lé tàbí ti òfin a máa ní awọn tí ń ṣe àrídájú ìwé lábẹ́ òfin lára àwọn òṣìṣẹ́ wọn.
- Ọ̀pọ̀ àwọn ilé-ìfowópamọ́ ni yóò le ṣe àrídájú àwọn ìwé lábẹ́ òfin àti pé iye owó tí a ó san kò pọ̀ rárá.

**Àwọn Mọ̀lẹ́bí**

- ☐ Ẹ̀dà ìwé-ẹ̀rí ọjọ́-ìbí fún ẹnìkọ̀ọ̀kan nínú mọ̀lẹ́bí
- ☐ Ẹ̀dà àwọn káàdì Ààbò Ìgbàlódé fún ẹnìkọ̀ọ̀kan nínú mọ̀lẹ́bí náà
- ☐ Ẹ̀dà ID àwòrán fún gbogbo ènìyàn tó ju ọdún 18 lọ (àpẹrẹ: ìwé àṣẹ ọkọ̀ wíwá, ìwé ìrìnnà, ID Ológun, ID Ìjọba Abẹ́lé NYC, ID àìkíìṣe awakọ̀)
- ☐ Ẹ̀dà àwọn lẹ́tà ilé-ìwé tí ń jẹ́rìísí ìforúkọsílẹ̀ fún ẹnìkọ̀ọ̀kan tí ń lọ sí ilé-ìwé (àwọn àpẹrẹ: Ilé ìwé ìjọba ti New York City, ilé ìwé àdáni, ilé ìwé gíga, ilé ìwé yunifásitì)

*[PAGE 3]*

***Báwo ni mo ṣe le bèrè fún àwọn ìwé ìdánimọ̀?***

## ÌWÉ Ẹ̀RÍ ỌJỌ́-ÌBÍ

Àkókò tí a ó fi Ṣiṣẹ́ lée Lórí: Ọjọ́ 2 sí Ọ̀sẹ̀ 8 | Iye owó: ~$15–$25

- Àwọn Ìbí New York City: Ẹ̀dà ìwé ẹ̀rí ọjọ́-ìbí ti ìjọba New York City ni a le bèrè lórí ẹ̀rọ ayélujára, lójúkojú, tàbí nípasẹ̀ í-méèlì nípasẹ̀ Ẹ̀ka Ilé-iṣẹ́ Ìlera àti Ìmọ́tótó Ọpọlọ ti Ilẹ̀ NYC. Iye owó wọn ni $15, pẹ̀lú $9 iye owó ìfíwéránṣẹ́ àti ti ìdíyelé iṣẹ́. Àwọn ìbéèrè orí ayélujára ni a ń ṣiṣẹ́ lé lórí láàrín wákàtí 24. Ṣàbẹ̀wò sí http://www.nyc.gov/doh tàbí kí o pe 311 fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé.

- Àwọn ìbí níbòmíràn ní United States: Àwọn ìwé ẹ̀rí ni a le bèrè lọ́wọ́ ọ̀ṣìṣẹ́ agbègbè tàbí ní ilé-iṣẹ́ àkọsílẹ̀ pàtàkì ti ìpínlẹ̀. Láti wá ilé-iṣẹ́ àwọn àkọsílẹ̀ ìpínlẹ̀ to ṣe pàtàkì, jọ̀wọ́ ṣàbẹ̀wò sí http://www.cdc.gov/nchs/w2w.htm tàbí kí o bèrè ìrànwọ́ ní ilé-ìkàwé àdúgbò rẹ.

**KÁÀDÌ ÀÀBÒ ÌGBÀLÓDÉ**

Àkókò tí a ó fi Ṣiṣẹ́ lée Lórí: Ọ̀sẹ̀ 2 sí 6 | Iye owó: Ọ̀fẹ́

- Mú ìwé ìbèrè kan ní ilé-iṣẹ́ Ààbò Ìgbàlódé àdúgbò rẹ àti/tàbí ní Gbọ̀ngán Káàdì. Láti mọ ibití ilé-iṣẹ́ àdúgbò rẹ wà, pe 1-800-772-1213 tàbí kí o lọ sí http://www.ssa.gov/cardcenters/cardcenterinfo.html.

**ID ONÍFỌ́TÒ TÀBÍ ÌWÉ ÀṢẸ ÌWAKỌ̀ TI ÌLÚ NEW YORK**

Àkókò tí a ó fi Ṣiṣẹ́ lée Lórí: Ọ̀sẹ̀ 2 sí 4 | Iye owó: $10–$80

- Kọ̀wé sí Ẹ̀ka Iṣẹ́ Ọkọ̀ ti Ìpínlẹ̀ NY láti bèèrè fún ìwé àṣẹ ìwakọ̀ tàbí ID onífọ́tò fún àwọn tí kìí ṣe awakọ̀. Ṣàbẹ̀wò sí www.dmv.ny.gov/license.html fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé, ṣàwárí ẹ̀ka ti àdúgbò rẹ ní http://www.dmv.ny.gov/offices.htm, tàbí kí o pe 1-212-645-5550 tàbí 1-718-966-6155 fún àlàyé.

**IDNYC: ÌDÁNIMỌ̀ AGBÈGBÈ ÌLÚ NEW YORK**

IDNYC jẹ́ káàdì ìdánimọ̀ ọ̀fẹ́ fún gbogbo olùgbé New York City. Ṣàbẹ̀wò sí www.nyc.gov/idnyc láti bẹ̀rẹ̀ ìkọ̀wé bèrè rẹ lórí ayélujára, tàbí kí o pe 311.

***Níbo ni mo ti le ṣe ẹ̀dà àwọn ìwé?***

- Ilé-ìkàwé Gbogbogbò ti Brooklyn: Pe 311 tàbí kí o lọ sí www.brooklynpubliclibrary.org

- Ilé-ìkàwé Gbogbogbò ti New York: Pe 311 tàbí kí o lọ sí www.nypl.org fún Bronx, Manhattan, àti àwọn ẹ̀ka Staten Island
- Ilé-ìkàwé Gbogbogbò ti Queens: Pe 311 tàbí kí o lọ sí www.queenslibrary.org
- Ilé-iṣẹ́ ìjọba ti àdúgbò rẹ: Pe 311
- Àwọn Ìsọ̀ ìtẹ̀wé àti ṣíṣe ẹ̀dà ìwé

*[PAGE 4]*

## ÀWỌN ÌWÉ OWÓ ÀPAWỌLÉ

Owó àpawọlé mọ̀lẹ́bí rẹ lọ́dọọdún jẹ́ "àpapọ̀ owó" tí gbogbo ẹni tó ju ọdún 18 lọ tí ń gbé pẹ̀lú rẹ ń gbà. "Àpapọ̀ owó " túmọ̀ sí iye tí agbanisíṣẹ́ rẹ san fún ọ ṣájú owó-ìlú. Àpapọ̀ owó rẹ máa ń sábà ju owó àmúrelé rẹ lọ. (Àkíyèsí: Tí o bá jẹ́ oníṣẹ́-àdáni, wàá jábọ̀ owó àmúrelé rẹ lẹ́yìn àwọn àyọkúrò.)

Gba gbogbo ìwé àkọsílẹ̀ tí o le gbà. IRS wípé àwọn ìwé ìsàlẹ̀ wọ̀nyí jẹ́ ẹ̀rí owó àpawọlé tí a le gbà. Pèsè ìwé owó àpawọlé fún gbogbo mọ̀lẹ́bí tó ju ọdún 18 lọ.

## ǸJẸ́ O NÍ ÀWỌN ÌWÉ WỌ̀NYÍ BÍ?

### *Kíni ìdí tí àwọn ìwé wọ̀nyí fi ṣe patàkì?*

HPD àti HDC nílò gbogbo àwọn ìwé wọ̀nyí láti jẹ́rìísí àpapọ̀ owó ọdún tí mọ̀lẹ́bí rẹ ń pa, àti lát lè ṣe ìṣirò iye rẹ – láti iṣẹ́ òòjọ́ àti àwọn orísun míràn.

**Owó Àpawọlé Iṣẹ́ Mọ̀lẹ́bí**

***Ǹjẹ́ ẹnikankan nínú mọ̀lẹ́bí rẹ ń gba owó oṣù tàbí owó wákàtí bí?***
Olùkọ́lé náà yóò sọ fún ọ irú àwọn ìwé tí o nílò. A ó bèrè àwọn nkan wọ̀nyí lọ́wọ́ rẹ, fún mọ̀lẹ́bí kọ̀ọ̀kan:

- ☐ Ẹ̀dà ìwé tó fi iye owó tí a san fún ọ nígbà mẹ́fà (6) tó kẹ́yìn hàn ní tẹ̀lé-n-tẹ̀lét
- ☐ Ẹ̀dà àwọn fọ́ọ̀mù W-2 ti ọdún tó kọjá (gbogb ojú-ìwé)
- ☐ Ẹ̀dà àwọn ìdápadà owó-ìlú tí ìjọba ìpínlẹ̀ àti àpapọ̀ láti ọdún tó kọjá, eyítí a buwọ́lù, tí ìwọ sì ti kọ àwọn ohun tó yẹ sí
- ☐ Ẹ̀rí ìsanwó (àwọn lẹ́tà àrídájú lábẹ́ òfin láti ọ̀dọ̀ agbanisiṣẹ́)
- ☐ Àwọn ìwé àtẹ̀jáde ti ilé-ìfowópamọ́ tó fi iye owó tí o san hàn

***Ǹjẹ́ ẹnikẹ́ni nínú mọ̀lẹ́bí rẹ ní iṣẹ́ àdáni bí?***
Fún mọ̀lẹ́bí kọ̀ọ̀kan tó ní iṣẹ́ àdáni, pèsè àwọn ẹ̀dà ti:

- ☐ Ẹ̀dà Fọ́ọ̀mù 1040 tí a buwọ́lù ti ọdún 3 sẹ́yìn, pẹ̀lú ètò C, E tàbí F
- ☐ Ẹ̀dà gbogbo àwọn 1099 láti ọdún 3 sẹ́yìn
- ☐ Ẹ̀dà ìdápadà owó-ìlú ìpínlẹ̀ ti ọdún 3

*[PAGE 5]*

**Owó Àpawọlé Mọ̀lẹ́bí Láti Àwọn Orísun Mìíràn**

O gbọ́dọ̀ ṣàfihàn àwọn ìwé nípa gbogbo owó tí o gbà, kódà tí kò bá jẹ́ láti iṣẹ́ tí o ṣe. Olùkọ́lé náà yóò sọ fún ọ irú àwọn ìwé tí o nílò. A ó bèrè àwọn nkan wọ̀nyí lọ́wọ́ rẹ, fún mọ̀lẹ́bí kọ̀ọ̀kan:

***Ǹjẹ́ ìwọ ń jẹ ànfàní tàbí ò ń gba owó àpawọlé tí a ṣàkójọ nísàlẹ̀ wọ̀nyí?***

Ẹ̀dà ìwé àkọsílẹ̀ fún:

-  (Àwọn) lẹ́tà àmì ẹ̀yẹ Ààbò Igbàlódé fún ọdún kàlẹ́ndà tó kọjá kẹ́yìn (èyítí iye ọjọ́ rẹ̀ kò tíì ju ọjọ́ 30 lọ)
-  Àwọn Ànfàní Arúgbó Ajagunfẹ̀yìntì (ìwé àkọsílẹ̀ ọdọọdún)
-  Owó àpawọlé láti àwọn ohun ìní tí a yá síta
-  Lẹ́tà Ètò Ìṣúná Ìrànlọ́wọ́ Ará-ìlú ti Àwọn Ológun tí a yà sọ́tọ̀

***Ǹjẹ́ ìwọ ń gba owó àjẹmọ́nú àti/tàbí owó ọdọọdún bí?***

-  Ẹ̀dà ìwé àkọsílẹ̀ láti (àwọn) ilé-iṣẹ́ aláṣẹ

***Ǹjẹ́ ìwọ gba ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ àti/tàbí owó ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ bí?***

-  Ẹ̀dà àwọn lẹ́tà àmì ẹ̀yẹ tó fi àkókò náà hàn

***Ǹjẹ́ ìwọ ń gba owó ìkọ̀sílẹ̀ aya/ọkọ àti/tàbí àtìlẹ́yìn fún ọmọ bí?***

Pèsè ẹ̀dà:

-  Ẹ̀dà ìpínyà tàbí (àwọn) àdéhùn ìparí ìjà tí ń sọ iye owó àti irú àtìlẹ́yìn àti ètò ìsanwó
-  Ẹ̀dà ìwé àkọsílẹ̀ ti ìjọba tàbí àtẹ̀jáde yòówù (tíiye ọjọ́-orí rẹ̀ kò ju ọjọ́ 120 sẹ́yìn lọ, tó sì ń ṣàfihàn ohun tó ṣẹlẹ̀ àti iye owó), tàbí ìwé ìbúra àrídájú lábẹ́ òfin.

***Ìdójútòfò abarapá, ìsanwó òṣìṣẹ́, àti/tàbí owó ìdópin iṣẹ́?***

-  Ẹ̀dà ìwé tó fi iye owó tí a san fún ọ nígbà mẹ́fà (6) tó kẹ́yìn hàn ní tẹ̀lé-n-tẹ̀lé tabí lẹ́tà ìjẹ́rìísí

***Ǹjẹ́ ìwọ ń gba àjọ àti/tàbí ẹ̀bùn àtìgbà-dé-ìgbà bí? Ǹjẹ́ ìwọ ń gba àwọn owó àtìgbà-dé-ìgbà mìíràn bí?***

-  Àkọsílẹ̀ àrídájú lábẹ́ òfin àti/tàbí ìbúra lábẹ́ òfin tí ẹni tí ń pèsè ìrànlọ́wọ́ náà buwọ́lù, pẹ̀lú èrèdí owó náà, àwọn déètì àti iye (àwọn) ẹ̀bùn náà, àti àwọn ìgbà tí a ń pèsè ẹ̀bùn náà (ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀, oṣooṣù, ọdọọdún).

- Àwọn àkọsílẹ̀ ilé-ìfowópamọ́ tó ṣàtìlẹ́yìn fún gbígbá àwọn owó wọ̀nyí

[PAGE 6]

**ÀWỌN ÌṢÒRO ÀMÚYẸ**

O gbọ́dọ̀ ṣe àkọsílẹ̀ àwọn ìṣòro yòówù tí o ti dojúkọ pẹ̀lú àwọn onílé rẹ tó ti kọjá tàbí pẹ̀lú gbèsè rẹ. Kódà pẹ̀lú àwọn ìwé wọ̀nyí, kò sí ìdánilójú pé ìwọ yóò kún ojú òṣùwọ̀n fún gbígba ibùgbé kan. A ṣì le kọ ìbèrè rẹ, kódà pẹ̀lú àwọn ìwé tó múnádóko.

**Àwọn Ìṣòro Onílé Tókọjá**

***Ǹjẹ́ onílé kankan tí pè ọ́ lẹ́jọ́ tẹ́lẹ̀ fún ìdí kankan bí?***
Tó bá jẹ́ bẹ́ẹ̀ni, mú àwọn ẹ̀dà ìwé wọ̀nyí wá:

- Gbogbo ìtọ́kasí òfin
- Àwọn ìdájọ́ ìkẹyìn yòówù lábẹ́ òfin
- Àwọn ìwé ẹ̀rí ìtẹ́lọ́rùn ìdájọ́ pẹ̀lú ilé-ẹjọ́

**Àwọn Ìṣòro Gbèsè Tókọjá**

***Báwo ni ìtàn gbèsè rẹ?***

Tí a bá yàn ọ́ fún ìpàdé kan láti ṣàrídájú àmúyẹ, gbèsè rẹ le ṣokùnfà àbájáde ìlànà ìpinnu náà. T

A kò le sọ wípé o ko yẹ nítorí iye gbèsè rẹ nìkan, ṣùgbọ́n àlàyé inú ìtàn gbèsè rẹ ṣe pàtàkì. Tí o bá ní ìwé àkọsílẹ̀ yòówù nípa gbèsè rẹ, o le fẹ́ láti gbàá ṣáájú àsìkò tí ìwọ yóò nílò rẹ. Fún àpẹrẹ:

- Lẹ́tà tó ṣàfihàn pé a ti yanjú àwọn ìṣòro gbèsè tàbí àwìn
- Ìwé ẹ̀rí ìtẹ́lọ́rùn nípa àsanpadà àwọn ohun tí a fi dúró tàbí ti ìtẹ́lọ́rùn ìdájọ́
- Iye owó tó kù nínú àkáùntì

-  Ìdájọ́ ìkẹyìn yòówù lábẹ́ òfin

Jọ̀wọ́ mọ̀ wípé pípèsè àlàyé yìí kìí`ṣe ìfọwọ́sọ̀yà pé ìwọ yóò yẹ fún gbígba ibùgbé kan.

Láti gba ẹ̀dà ọ̀fẹ́ ìjábọ̀ gbèsè rẹ, ṣàbẹ̀wò sí http://www.annualcreditreport.gov.

Láti ráyèsí àwọn iṣẹ́ ìrànlọ́wọ́ ìṣúná owó fún Àwọn Olùgbé New York, pe 311 tàbí kí o ṣàbẹ̀wò sí nyc.gov/consumers.

Ṣàbẹ̀wò sí www.nyc.gov/housingconnect láti rí ọ̀pọ̀ àlàyé tàbí láti kọ̀wé bèrè lórí ayélujára.

*[FOOTER]*



Ṣàbẹ̀wò sí www.nyc.gov/housingconnect láti rí ọ̀pọ̀ àlàyé tàbí láti kọwé bèrè lórí ayélujára.

Àkọsílẹ̀ yìí wà fún èrèdí àlàyé nìkan. Èyí kìíṣe ìbèrè fún ilé àìwọ́n. Kíkọ àwọn ohun tí a bèrè fún sínú ìwé yìí kìíṣe ìdánilójú pé ìwọ yóò gba ibùgbé àìwọ́n kankan.